# Ìfètòsọ́mọ bíbí Alábẹ́rẹ́ Olósùmẹ́ta

# (Depo-Provera)




**Àlàyé nípa rẹ̀:**

- Alábẹ́rẹ́ jẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí tí a ma ń gbà ní osù mẹ́ta mẹ́ta láti dènà oyún
- O lè bẹ̀rẹ̀ ní ọ̀sẹ̀ mẹ́fà lẹ́yìn tí a bímọ, kòsì léwu fún obìnrin tí ó ńfún ọmọ lọ́yàn
- Ó lè fa kí ǹkan oṣù máa se ségesège tàbí kí ó má wa
- Kò dènà àrùn ìbálòpọ̀ tàbí HIV
- Kò léwu fún obìrin tó ń gbé pẹ̀lú àrùn HIV/AIDS yálà ó ń lo ògùn tó ń ṣèdíwọ́ fún kòkòrò tó ń fa éèdì

**Bí ó ti lè dènà oyún sí:**

- Ní ọdún kíní lílò rẹ̀, óseése kí obìnrin kan nínú ọgọ́run lóyún bí wọ́n bá lò ó dáadáa lái pa osù kankan je tàbí gba abẹ́rẹ́ pẹ́ (1%)
- Bí wọ́n bá pa abẹ́rẹ́ je tàbí kí ó pẹ́ kí wọ́n tọ́ gba òmíràn, óseése kí obìnrin mẹ́ta nínú ọgọ́run kí ó lóyún (3%)

**Bí óse ń ṣiṣẹ́:**

- Ìfètòsọ́mọ bíbí alábẹ́rẹ́ ní èròjà ara (progestin) nìkan nínú
- Progestin á ma mú kí ikun tí ówà ní enu ọ̀nà ilé ọmọ kí ó ki, èyí yí ò dènà kí àtò okùnrin má lè wọ ilé ọmọ
- Èròjà ara yí kò ní jẹ́ kí obìnrin yé ẹyin tí ópọ́n (àsìkò yíyẹ́ ẹyin obìnrin lósoòsù)
- O gbọdọ̀ gba abẹ́rẹ́ yìí ní ẹ̀ẹ̀kan láàrín osù mẹ́ta mẹ́ta

**Àkíyèsí pàtàkì:**

- Ìlànà yí se é yípadà. Alè da dúró nígbà kugbà, yálà láti bọ́ sí òmíràn tàbí láti lóyún
- Ìlànà yí ní àsírí bíbò, ẹnikẹ́ni kò lè mò bóyá o ń lo ìlànà yí
- Kò fa ìdíwọ́ kankan fún ìbálòpọ̀ lọ́kọ láya

**NOTE:**
**Lẹ́yìn tí a bá ti dá ìlànà yí dúró, àti lóyún yàtọ̀ láti obìnrin sí obìnrin láàrín oṣù mẹ́fà sí ọdún méjì**

**Nítorí náà, obìrin lè yíjú sí ìlànà tó ní àsìkò péréte tí ó bá fẹ́ lóyún láìpẹ́.**

Get it together
KNOW. TALK. GO.



## Ìlànà yí kìí se fún o:

- Bí o bá ńfún ọmọ tí kò tí pé òsẹ̀ mẹ́fà lọ́yàn
- Bí o bá ní ìfunpá gíga
- Bí o bá seése kí o ní àrùn tí o ní se pẹ̀lú ẹ̀jẹ̀ rúrú, sísanra jọ̀kọ̀tọ̀, àìsàn arúgbó, àti àrùn ọkàn (bá akọ́sẹmọ́sẹ ìfètòsọ́mọ bíbí rẹ sọ̀rọ̀ lẹ́kùn rẹ́rẹ́)
- Bí o bá ní kókó nínú ọyàn (jejere) tàbí enikéni nínú ẹbí rẹ ti ní kókó nínú ọyàn rí.
- Bi ẹ̀jẹ̀ tí a ko lè ṣàlàyé bá ń jáde ní ojú ara rẹ
- Bí o bá ń lo ògùn fún gìrí tàbí ògùn ikọ́ ife rifampicin (eleyi ko ni je ki ìfètòsọ́mọ bíbí yi ṣiṣẹ́)
- Tí o bá ní àrùn tí óní ṣe pẹ̀lú ẹ̀dọ̀ àti ẹ̀dọ̀foro

## Àwon Àpẹẹre tó lè jẹyọ:

- Ní ìbẹ̀rẹ̀, ǹkan oṣù ma ń se ségesège, kí ọjọ́ rẹ̀ pọ̀, kí o má wa léra léra, kí ó sì pọ́n tí ó bá pé, ó lè má wa rárá
- Ìyípadà nínú ǹkan oṣù yí lèmá parí títí ẹ̀yin oṣù méjì sí mẹ́ta tí alábẹ́rẹ́ bá ṣiṣẹ́ tán
- Àwọn obìnrin míràn lẹ̀ máà tóbi si , ní orífifọ́ tàbí òyì, èléyìí kò ní ewu, kìí se àmì pé àrùn míràn wà lára.
- Kìí se gbogbo obìnrin ni yíò ní àwọn àpẹẹre wònyí

## Ààfàní fún ìlera:

- O lè dènà àrùn jejere awọ inú ilé ọmọ
- O lè dènà ìju inú ilé ọmọ
- O lè dènà àwọn àrùn tí ó níse pẹ̀lú ilé ọmọ
- O lè dènà àìsàn àìtó ẹ̀jẹ̀ nínú àgọ́ ara
- O lè dínkù àwon àmì tí ó ń jẹyo fún edometriosis (bí inú kíkan , ǹkan oṣù tí ó ń se ségesège)

## Bí aṣe lè lò ó:

- Lo sí ilé ìwòsàn ìfètòsọ́mọ bíbí láti gba abẹ́rẹ́
- Má a gba abẹ́rẹ́ rẹ ní osù mẹ́ta mẹ́ta. Bí okò bá gba abẹ́rẹ́ rẹ tí o sì ní ìbálòpọ̀, o lè lóyún
- Bí o bá tilẹ̀ pé ọ, lo sí ọ̀dọ̀ akọ́sẹmọ́sẹ ìfètòsọ́mọ bíbí láti gba abẹ́rẹ́ míràn

## Rántí wípé:

- Padà sí ilé ìwòsàn ní oṣù mẹ́ta fún abẹ́rẹ́ míràn
- Ri wípé ò ń se dédé
- O lè padà wá bí ó bá ku òsè méjì kí àkókò abẹ́rẹ́ rẹ tó pé
- Bí o tilè wù kí ó pẹ́ tó, bèrè lọ́wọ́ akọ́sẹmọ́sẹ ìfètòsọ́mọ bíbí igba tí ó lè wá láti gba abẹ́rẹ́ míràn
- Bí o bá ti pẹ́ láti gba abẹ́rẹ́ míràn, yẹra fún ìbálòpọ̀ tàbí kí o lo rọ́bà ìdábòbò títí ìwọ yóò fi gba abẹ́rẹ́ míràn

## Padà lo sí ilé ìwòsàn bí:

- O bá ni ìbéèrè tàbí ìsòro kankan
- O bá nílò abẹ́rẹ́ míràn
- Isòro kan bá jẹyọ nínú ìlera ara rẹ
- O bá kùnà láti gba abẹ́rẹ́ míràn, ní àsìkò tí o sì ti ní ìbálòpọ̀ láàrín ọjọ́ máàrún sẹ́yìn, o kò sì fẹ́ láti lóyún
- Bí ó bá lérò pé o ti lóyún

This material is adapted from a similar material by Society for Family Health (SFH)